# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LA WA

No. 574 WEDNESDAY APRIL 8, 1964 (2D)


## Ijoba Da Awọn Ọmọ Ile Ẹkọ Duro

ILESHA:— Ni kutukutu owurọ ana ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni iwe aṣẹ jade lati Ile–iṣe Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S. L. Akintọla pe, ki Ijọba da irinwo (400) awọn ọmọ Ile-ẹkọ Ilesha Grammar School duro fun igba diẹ na, atipe, ki Ijọba si ti ile–ẹkọ na.

Ohun ti o fa eleyi nipe, ni ọjọ Abameta ti iṣe ọjọ kerin oṣu yi ni Oloye Akintọla ati Fani-Kayọde lọ si Ilesha lati fi idi ẹgbẹ Demo lelẹ, ṣugbọn nigbati nwọn de iwaju Ile–iwe na ni awọn ọmọ Ile–iwe na ba kigbe le wọn lori pe, "Ole! Ole!! Ole!!!" ti gbogbo awọn ara ilu fi sare jade ninu ile, nitorire nwọn ṣebi nwọn mu ole kan ninu ile-ẹkọ na ni.

Ijọba ti da Ọga Agba ile ẹkọ na duro, Alufa J. A. Akinyẹmi duro, nwọn si ti tun da gbogbo awọn ọmọ Ile ẹkọ na duro, pe ki nwọn o ma a lọ si ile fun igba diẹ na.

Ijọba si ti yan awọn igbimọ kan ti yio ṣe iwadi ohun ti o fa a ti awọn ọmọ Ile iwe na fi hu iru iwa bẹ ni ọjọ na. Oniwe irohin wa kan fi ye wa pe awọn ọmọ Ile ẹkọ na ti bẹrẹsi to ẹru wọn jade, olukuluku awọn ọmọ na lọ si ile titi ti Ijọba yio fi pe wọn pada enia mẹtadinlogun ẹlo farahan niwaju adajọ lana, nwọn si sọ wipe awọn ko jẹbi ẹsun ti Ọlọpa mu awọn fun.

# AWỌN ARA ILU FẸ GBA AAWẸ ỌJỌ MẸTA FUN OLOYE AWOLỌWỌ

## Iranlọwọ Adura Atọkanwa Fun Awọn Adajọ

ABA:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa ti nwọn wa ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria nigbati nwọn se ipade kan nilu Aba ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ karun oṣu yi.

Irohin fi ye wa pe, gbogbo awọn ọmọ Yoruba ti nwọn wa ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ni nwọn wa sibi ipade na lati awọn oniruru ilu bi Ẹnugun, Kalaba, Uyo, Port–Harcourt, Onitsha, Awka, Umuahia, Bende, ati bẹbẹ lọ.

Awọn ọmọ Yoruba ti o wa ni Ipinle na ti gba wipe, gbogbo awọn ni ọmọ ẹgbẹ Oduduwa nitoripe, Oduduwa ni baba nla ti o ṣe gbogbo awọn ọmọ Yoruba silẹ.

Lẹhin ọpọlọpọ ifọrọwerọ, awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ohun ti o nṣẹlẹ nisisiyi si awọn ọmọ Yoruba, o fẹ amojuto paapa julọ ọran Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, ẹniti iṣe akọwe Agba fun ẹgbẹ ọmọ Oduduwa, ati eni ti o da ẹgbẹ na silẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na wa kesi gbogbo enia jakejado Naijiria pe, ki nwọn gba Aawẹ ọjọ mẹta fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ẹniti ẹjọ rẹ yio bẹrẹ ninu Ile-ẹjọ giga julọ Naijiria ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ wa ni awọn ni igbagbọ ninu adura, awọn si gbagbọ pẹlu pe, ko si oke iṣoro kan, ti adura ko le sọ di pẹtẹlẹ.



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**
Akọwe Agba Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa

Nwọn si ṣe ipinnu wipe, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa ti awọn wa ni Ipinle Ila Orun Naijiria ni awọn yio gba Aawẹ ọjọ mẹta pẹlu akanṣe adura fun oloye Awolọwọ, ki o le ba ṣẹgun ẹjọ ti Ijọba mba ṣe.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun gba ninu ipinnu wọn wipe, ọjọ ti ẹjọ Oloye Awolọwọ yio bẹrẹ gan an, ni awọn yio bẹrẹ aawẹ na Eyi si ni ọjọ Ẹti, ọjọ Abamẹta ati ọjọ Aiku ti mbọ yi.

Awọn ọjọ wọnyi bẹrẹ lati ọjọ kẹwa oṣu yi ọjọ kọnkanla ati ọjọ kejila oṣu yi.

Awọn enia na ṣe ileri pe awọn ko ni jẹun fun awọn ọjọ mẹtẹta wọnyi awọn yio si kun fun adura fun gbogbo ọjọ na pe ki Ọlọrun tikala arare o le fi ti oke Ọrun fun Oloye Awolọwọ ni akotun agbara ki o si fun un ni ẹmi igboya ni gbogbo asiko ẹjọ rẹ eyiti yio bẹrẹ ni ọjọ kẹwa oṣu yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na wa kesi gbogbo awọn enia Naijiria l'ọkunrin ati l'obinrin paapajulọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ.

Ni opin ọrọ wọn, gbogb awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwọn ṣe ileri pe awọn yio tun ma a gbadura pataki pe ki Ọlọrun o le ṣe Oludari gbogbo awọn adajọ ti nwọn yio joko lori aga idajọ na, ki Ẹmi Mimọ o le ma dari wọn.

Ki awọn ọmọ ẹgbẹ na to mu ipade wọn ọjọ na wa sopin, nwọn fi ẹnu ate lu ẹgbẹ Dẹmọ ti o nṣe akoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fun dida ti nwọn da Ogunde duro lati ma a se iṣẹ onjẹ oojọ rẹ.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na ni iru iwa idaduro yi ko dara to, nigbati o jẹ wipe ọmọ Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ti elere Ogunde iṣe, ki iṣe alejo ni Ipinlẹ na.

Awọ ọmọ ẹgbẹ na ni, nigbati Ijoba nṣe iru elevi si awọn ọmọ ti a bi ni Ipinlẹ na kini o wa ku ti nwọn fẹ ṣe si awọn "ero Bodo–o–wa"?

Nwọn ni iwa na ko dara to rara, ṣugbọn awọn ọmọ ẹgbẹ na ni ṣẹ fun Alaga wọn ọgbẹni Muṣibau Ọdẹbiyi pe ki o kọwe si Hubert Ogunde, ki o wa ṣe are "Yoruba Ronu" na fun awọn ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria

Oniwe irohin fi ye wa pe akọwe ẹgbẹ na ti kọwe si Ogunde, ṣugbọn a ko ti mọ ọjọ ti Ogunde yio lọ ṣere na ni Ipinlẹ Ila Orun.

Awọn ọmọ ẹgbẹ (A. G.) Afẹnifẹre ọdọ ti nwọn wa ni Ibadan ati agbegbe rẹ sọ ninu ipade kan ti nwọn ṣe ni alẹ ana wipe, ọsẹ kan gbako ni awọn yio fi gba adura fun Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ẹjọ rẹ yio bẹrẹ ni ọtunla ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ na wa kesi gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati gbogbo awọn ti o ni ifẹ ẹgbẹ na lọkan, lati kun fun adura ninu ọsẹ yi, nitoripe gẹgẹbi awọn ọmọ ẹgbẹ na ti wi, "Ko si ohun ti o le, ti adura ko le mu rọ."

Ni ipari ọrọ awọn ọmọ ẹgbẹ na, awọn tun kesi gbogbo awọn ara ilu pe ki nwọn o kun fun adura ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ti ẹjọ Oloye na yio bẹrẹ, ki iranlọwọ lati oke ọrun ki o le ba awọn adajọ ati olujẹjọ pẹlu awọn olufisun.

# Ọwọ Awọn Ọlọpa Tẹ Ọgọrun Aṣẹwo

ONITSHA:— Ọrọ di bi o lọ ya fun mi nigbati awọn ọlọpa ya wọ inu agbo ile nla kan ni arọ kutukutu ọjọ Ru ti ṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu ti o kọja yi. Were awọn ti o ti ji ninu awọn obinrin aṣẹwo (Koforun) ti o wa ninu ile yi sare wọle ti nwọn si nji awọn ti koi ti ji jade ṣugbọn ọwọ ọlọpa ni nwọn bọ si wẹrẹ bi nwọn ti fẹ maa lọ.

Agbọ wipe ọgọrun obinrin ni ọwọ awọn olọpa tẹ pẹlu awọn kan ti nwọn fi ara ban pe awọn lo kọ wọn jọ sinu ile na.

Gẹrẹ ti awọn ọlọpa mu awọn Aṣẹwo yi tan ni Ọga ọlọpa kan sọ fun onirohin wa pe ohun ti awọn ṣe yi ni lati le fi opin si awọn kan ti ko fẹ lati fi ọwọ wọn ṣe iṣẹ ti nwọn si mba awọn ọdọmọbinrin jẹ

Ọga ọlọpa na tun fi kun ọrọ rẹ pe o ti wa si eti gbọ awọn pe awọn ọpọlọpọ ile ita ọti ni o wa (Hotels) ti o jẹ pe awọn obinrin ni awọn gba sibẹ lati le ba ilu jẹ.

Awọn si ṣetan lati fi opin si iru iwa buburu yi A lero pe awọn ọ l ọ p a yio ba awọn aṣẹwo ti nwọn mu na ṣejọ laipẹyi ṣugbọn bi nwọn ba ti pari rẹ si, ẹ o maa gbọ o.

## Ẹma ka Irohin Imọlẹ lojojumọ

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan22-Feb20) Isoro ni yio jẹ fun ọ lati ba enia ṣe ọrẹ loni, maṣe fi ara rẹ joye ariteni mọwi.

PISCES (Feb21-Mar.20) Mura l a t i ṣ e atunse gbogbo edekyede ti o wa nile. Ohun kan ti i w ọ ko nireti yio ṣẹlẹ ni akoko ọsan.

ARIES (Mar.21-Apl.20) Afojudi ati orikunkun yio ba nkan pupọ jẹ fun ọ loni, Maṣe alakọkọ ninu ohun gbogbo.

TAURUS (April 21-May20) Sọra rẹ jọjọ loni, ki o si ranti ara rẹ mọṣe jagbọn ko kan mi, tabi imọtara ẹni nikan

GEMINI (May 21-June 21) Iwọ yio gbọ irohin kan ni ọjọrọ, enikan yio m a yọ ọ lẹnu loni, maṣe kania ni toai

CANCER (June 22-July 23) Iwa ti ẹlomiran yio ma hu si ọ loni ko ni jẹ ohun to ba ọ lọkan mu Sɐru nigbọ.

LEO (July 24 - August 24) Orisirisi yio pọ ninu aniyan rẹ loni ọrọ kan ti ẹjọ sọ lefa ijọgbọn wa ba ọ loni

VIRGO (Aug 25 - Sept 21) Iwọ yio ṣe ọpọlọpọ iṣẹ re loni, sugbọn arẹ yio mu ọ loni diẹ.

LIBRA (Sept 22 – Oct 23) Inawo airotẹlẹ yio de si ọ Ma wadi ọrọ wo daradara ki oto ma jalu gbogbo nkan ti ọkan rẹ daniyan ni yio yanju.

SCORPIO (Oct. 24 - Nov 22) Arẹ yio mu ọ de ipọ ti ara rẹ ko ni fẹ iṣẹ lati ṣe, sugbọn maṣe sahun ki Mọlẹ le gbe ọ

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 22) Iṣoro kan yio wa fun O bẹ i nigbehin ara yio rọ ọ.

CAPRICORN (Dec 23 - Jan 21) Maṣe jẹki gbogbo nkan ti o ba wu ọ ni ki o ma nawo si


BI O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TETE KỌWESI ILE—IṢẸ ẸRỌ—ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**

16 Bamgboşe Street, P. O. Box 1495

Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN

*OWO PỌKU NI A SI NGBA*

IROHIN KO TO AFOJUBA

*Dan wa wo lẹẹkanşoşo ki o si ri iyatọ*



# AKARA TU S'EPO!

## Iwe tumọ Ala na ti de

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Igo kan 5/
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N /99 Shittu Street
Ibadan



# Congreves' Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara Inu gbigbona nigbakugba

Igba — aiya riru ọmu riro, didun arẹ atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfori abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati orişirişi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Orisirisi rọbirọki egbogi ti wọn nko wa sisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orerẹ lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan re bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ilo-itọ tabi se iwosan iyọuu apo-ile-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati orişirişi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, Palm Church Street, Lagos.
Phone:h Nigeria, (Ọja Ita Faji)

# GunnuGun Ṣore, O Pa L'ori

Lati Qwọ:- Ẹsọ, Eko,

Inu mi yio dun bi Olotu ba le gba mi laye ninu iwe irohin rẹ lati sọ itan kekere yi fun awọn onkawe wa ki nwọn o le ri ẹkọ ti o wa ninu itan na kọ, ki nwọn si mọ idi Owe ti awọn Baba wa maa npa ni ayie atijọ wipe, awọn gunnugun sore, nwọn pa lori.

Iyan mu, mu, mu, o pa Ọba Olomu, opa igba ẹran-ko, o pa Agbagba mẹfa, ojo pata, pata, pata, ja bọ silẹ, Ọmọ adiẹ sare sii, o ṣebi agbado mi.

Tabi ṣe o na ni no jare, iyan mu lakoko na, ti ofi jẹ wipe, iṣu ko ta, agbado ko gbo, ojo kọ ko rọ Idamu ba araiye, Araiye ko rohun jẹ, ọrun ko ri ẹ'ọ abi etutu gba, bi nwọn ti nkigbe nile aiye, bẹni ero ọrun nlọboso.

Ọlofin wa se ikede fun gbogbo awọn ọdẹ ki nwọn mura lati wa lọ ba ara ọrun ja. Bi o ba le dogun ko di ogun, bi oba si le dija to fẹ o le dija ki di ibinu ojo iba pa ewe koko, bo le ya ko ya. Aṣe bi a ti nṣe nile aiye bẹna ni nwọn nṣe lode ọrun.

Ṣamọ-ṣamọ bi awọn ọdẹ aiye ti ngbimọran yi bakanna ni awọn ọde ọrun ngbimọran lati lọ digbolu awọn ọde aiye.

Awọn ọdẹ aiye mura nwọn si gun nwọn nlọ ba awọn ode ọrun ja Ọde ti ko ba gboju ko gbọdọ ba wọn lọ si ogun na. Diẹ ninu awọn ohun ija ti nwọn mu dani ni ọnyi, Akaraba, Abatampo, Aluse Ẹfagun Ofa Kondo Aluki Oruka Atare Afẹri Egbe Yọke-yọke kumọ, ati awọn ohun ija bawọnni. Nigbati nwọn fẹ wọ inu igbo mọlẹ awọn Ọde ti ko mọwọ ti ko mẹsẹ pada sẹhin.

Nitoripe ninu igbo mọlẹ yi Ogun lọgọ enia lo ti sọnu gbere ti nwọn ko gburo wọn mọ titi di oni nitoripe o toju ibiti enia ko gbọdọ de o si loju ibiti enia ko gbọdọ te mọlẹ.

Bi awọn ọdẹ Aiye ti nfi ibinu ati igbenu Oogun tẹ si iwaju ninu igbo Mọlẹ nwọn de ẹnu Ala Araiye ati Ala Ọrun konge ni nwọn nişe pẹlu awọn Ọdẹ Ọrun ti awọn na mbọwa ba ọde aiye ja.

Awọn Ọdẹ aiye nsujala, bẹni awọn Ọde Ọrun na nsujala. Nititi iọtun tosi wọn ti nsujala nibẹ ni awọn ọde ọrun gbe ti sọ ohun ti Aiye fi ṣe O u ayafi ki ariye ṣe etutu ki nwọn gbe wa sọdọ Olodumare ni gba na ara yio rọ aiye, ọrun yio si baiye, iọtun tosi wọn si gba lati ṣe bẹ.

Ki nwọn to tuka lọjọ na awọn Ọdẹ ọrun sọ wipe iru apejọ ti nwọn ṣe loni, iru rẹ ko waiye ri, nitori na o yẹ ki awọn Ọdẹ mejeji gba ofin kan sihin ohun kohun ti o ba ja sinu ofin na ki ẹ pin simeji, ki awọn ara ọrun mu ti wọn ki araiye mu ti wọn. Nwọn pa imọ pọ nwọn si sebẹ gbogbo wọn si tuka, araiye pada sile aiye, ara ọrun si dẹhin si ọrun.

O sise ni ọjọ keji, ẹran Edu kan ja sinu ofin na Ọdẹ aiye lo si kọkọ de ibẹ, Opa ẹran edu na, o pin si meji, omu ti awọn Ọdẹaiye lọ, o fi ti Ọde ọrun silẹ, awọn Ọdẹ ọrun de ibẹ, nwọn ba ti wọn, nwọn si mu lọ.

Li ọjọ keji, ọkan ninu Aja Ọdẹ ti awọn Ọdẹ Aiye ti oba wọn lọ sigbo Mọlẹ, ti osi sọnu sọhun ja sinu ofin na. Awọn Ọdẹ ọrun lo kọkọ de ibẹ, nwọn ge Aja na si meji nwọn si mu ti Ọdẹ ọrun lọ.

Nigbati Ọdẹ aiye de ibẹ, inu wọn bajẹ nigbati nwọn ri pe, Aja Olori Ọde lo ko sinu ofin, inu bi Ọde aiye jọjọ o wipe howu! awọn Ọdẹ ọrun yio ha sọ pe nwọn ko mọ pe aja Ọdẹ Aiye niyi, nwọn si dakẹ, nwọn mu lọ.

Lọjọ kẹta Ọde Aiye lo kọkọ de idi ofin, osi ba ọkan ninu iya awọn Ọdẹ ọrun, nwọn ko beni, beji, nwọn bẹ si meji wọn si mu ti Ọde aiye lọ. Nigbati awọn Ọdẹ ọrun de ibẹ, ti nwọn ri iṣẹ ti awọn Ọdẹ Aiye ṣe inu wọn bajẹ Agba do ti o nfẹ gbo, tun pada wo ve gbogbo igi oko wowe danu' Eyi ni anpe ni igba ẹrun titi di oni, koiti pari.

Wo Oju Ewe Kẹfa

## LATI OJU EWE KEJI

Lọgan nwọn ti wa atare lọ, nwọn ri to mẹfa nigbati odi ọganjọ oru ni ọkunrin yi ba da ẹyọ atare mẹsan si ẹnu o wa bẹrẹ ofọ rẹ pe, "Akifi ele pa ito o, a ki yọ ida ka fi bẹ esinsin lori, lowọlowọ ni teran bejẹ, ago lọna komọ Olufẹ oribi lọ, ago lona, ẹo mọ gbọ bi nwọn tise pa b balorisa ti nwọn si bọ lọwọ ik ẹlẹ— keji.

AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid-Ul-Kabir Dance**

AT

FORSTER CENTENARY HALL

22, Ọduniami Street, Lagos. On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest beats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/- Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọle's Office Wemimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Metta.

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

**RICHELET**

FUN ARUN ẸJE ARA ENIA GBOGBO



Eleyi yato patapata si awọn Robi-robi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA ti Mọnmọnọ

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọkuadimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyen ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi.

Gẹgebi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Iatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ ba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ehin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbon RISALETI a ma a pa gbogbi kokoro buruku ti o wa nbẹ ẹje ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pelu

BERE OJULOWO EGBOGI:—
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 574 WEDNESDAY, APRIL 8, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi enipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imole Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ. Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati odun meje 957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori radio fun gbogbo enia lati gbọ sugbọn eniti o ba tun fẹ alaye lori ọro yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni ọọmba,

16, BAMGBOṢE STREET.
PHONE 21985. LAGOS.

# ỌGBẸNI BENSON KỌWE SI OKPARA

EKO:— Igbakeji Olori ẹgbẹ Alakukọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si ṣe waya si Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati lori ẹgbẹ Alakukọ Dokita M. I. Okpara fun rogbodiyan to bẹ silẹ ni ọsẹ to koja ni ile iṣẹ ọkọ Reluwe lati le da si ọrọ na ati nipa did duro ti wọn da igbakeji ga agba ti ile iṣẹ na Ọgbẹni Modupẹ Alade.



Ọgbẹni T. O. S. Benson

Ipe ti ọgbẹni Benson si fi ope Dokita Okpara ni lati da si ọrọ na ati da alaga ile iṣẹ na Dọkita Ukechukwu Ikejiani lati da duro fun iwa ti O nhu si awọn Yoruba ati yio mu ipalara wa fun ẹgbẹ wọn.

Ọgbẹni Benson si sọ pe dida ọgbẹni Alade duro lẹnu iṣe si jẹ Ibẹrẹ iwa buburu si awọn ọmọ Yoruba

Ọgbẹni Benson si sọ ninu ọro rẹ pe on si ti gbọ pe Dokita Ikejian si ti fi ọgbẹni Alade ṣe ẹnikini ninu awọn ọmọ Yoruba to jẹ ọga ni ile iṣẹ Relowe.

Ọgbẹni Benson si sọ pe wọn ko fun ọgbẹni Alade laye lati ṣe alaye igba ara rẹ sile ati pe wọn ko [illegible] fun ni asiko kan ki wọn to daduro lẹnu iṣẹ,

Ọgbẹni Benson si sọ pe iru iwa ti Dokita Ikejiani nhu yio mu iyasọtọ wa fun ẹgbẹ N. C. N. C. ni ipinlẹ Iwọ Oru Naijiria.

Ọgbẹni Bẹnson si tun sọ ṣii gẹgẹ bi igbakeji Alakoso ẹgbẹ Alakukọ ni ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria pe ko si jẹ ẹdun ọkan on lati ma ri pe awọn Yoruba to wa ni ile iṣẹ Reluwe si nri inira ati aifi ọkan bale.

Idarudapọ si wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ to wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Ọgbẹni Benson si tun so pe Dọkita Ikejiani ko si ni itẹriba fun Dọkita Okpara ti o ti si aye na gẹgẹbi Alaga ile iṣẹ ti Reluwe, Ati pe Dokita Ikejiani si tun nṣe igberaga pe on lo ba ṣe Olotu Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ati pe eleyi si jọ iwa ilodi ati aini itẹriba.

Ọgbẹni Benson si tun sọ si i pe on ro pe Dokita Ikejiani yio tun gba Dokita Okpara gẹgẹbi Asiwaju ọmọ ẹgbe Alakukọ ati gẹgẹbi Olotu fun Ipinlẹ Ila Orun Naijiria.



Dokita M. I. Okpara
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

Akọwe agba fun ẹgbe ọmọ Ọlọfin Oloye H. O. Davies si ti ke si Are ilẹ Naijiria Dọkitọ Nnamidi Azikiwe ati Olotu Ijọba apapọ Ọlọla Abubakar nipa gẹgẹ bi nkan ṣe nlọ si ni ile iṣẹ Reluwa. Ninu ọrọ Oloye Davies, o si sọ pe ti wọn ba le fi Dọkita Ikejiani silẹ lati jẹ ki o ma hu iru iwa buburu bayi si awọn ọmọ Yoruba pe yio jẹ nkan ti yio mu ipalara wa fun asepọ to wa larin awọn Ibo ati Yoruba Ilẹ Naijiria.

## Gunnugun Ṣore.

Lati Oju Ewe Karun

Nigbati awọn araiye ri bayi, nwọn ranti etutu ti awọn ọdẹ oru sọ fun wọn wipe ki nwọn ṣe, ni nwọn ba ṣe etutu na pari, o wa ku ẹniti yio gbe ẹbọ na lọ si iwaju Olodumare Ki si ọkan ninu awọn Irunmẹti o le gbe ẹbọ na lọ si akaka Olodumare

Nwọn ranṣẹ lọ pe Akalamagbo abi gẹgẹ Ọlọrun ki o ba wọn gbe ẹbọ na lọ si ọrun. Nigbati o gbe, ti o fo koja idaji Sanma, ọrun wọ ọ, ko le lọ mọ, lo ba pada silẹ. Nwọn tun ranṣẹ lọ pe Awodi, Awodi lọ. o tun pada sẹhin gbogbo awọn ẹiyẹ lo kọ lọ. Nwọn wa ranṣẹ lọ pe eiyẹ Gunugun, o si ṣeleri pe on yio lọ

Ọlọfin ṣeleri fun pe bi o le gbe ẹbọ na de ọhun, ẹran ara rẹ yio di ewọ fun gbogbo araiye. Bẹni Gunugun ba gbe ẹbọ na, o fo, o si nlọ.

Nigbati o gbe ẹbọ na de sanmọ, ti o nra dẹgi, awọn araiye bẹrẹ si rawọ, rasẹ fun. Ayani, o ri i, lati ọjọ na ni awọn araiye ti nrawọ rasẹ lati fi be Olodumare.

Bi Gunugun ti gbe ẹbọ na de ajule ọrun, bẹni ojo kan kiki ki o to wipe Gunugun de ile aiye, ojo ti bẹrẹ si rọ, olukuluku enia si ti tilẹkun mọri tobẹ nigbati Gunugun pada de ilẹ. ko si ẹniti o ṣilẹkun fun.

Orun pa awọ ori re bo titi de ọrun rẹ, nitori idi eyi ni nwọn fi nsọ pe Gunugun ṣore, o pa lori,


## AKARA TU S'EPO!

### Iwe Itumọ Ala na ti de!!

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imolẹ pe Iwe Itumo Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pelu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Iwe kan 5/-
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N./99 Shittu Street
Ibadan



Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street P. O Box 1495 Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) Bariga Lagos (8/4/64)